THE EDITOR IMOLE OWURO
26/3/77
IBADAN.

WEEKS 35&36
Kongi WK 35
32 39 40
Wk 36
5 14 15
Asiko BK WK 35
9 10 12 13
Wk 36
19 20 21 23
Ross Wk 35
4 & 20
WK 36
7 &33

# Imọlẹ Owurọ

ẸSIN ỌRỌ WA: IMỌLẸ DE OKUNKUN PARADA!

SAMCO OF NIGERIA
WK 35
NAP 4 20 25
Perm 4 20 25 28 43
My Address
N4/496B
Yemetu Aladorin
IBADAN.
12 35 42
Nap

29 MAR

Independent Paper Vol. XV NO 791 SATURDAY MARCH 26 – FRIDAY APRIL 1, 1977 10K. (KOBO MEWA)

# 'ỌMỌ BABA MẸFA FUN 'AJẸ' NI OMI OKU MU'



ỌGAGUN IKPẸMẸ
Gomina Ondo

## Oluko Yoruba

ALAKOSO Ọran Ẹkọ fun Ipinlẹ Ondo, Dokita Kọla Fọlayan, ti kẹdun pe, awọn olukọ ede Yoruba ko to nkan ni ile ẹkọ giga Girama ati ti ikọṣẹ olukọni ni Ipinlẹ Ondo.

Dokita Fọlayan sọrọ yi nibi ifilọlẹ Ẹgbẹ Akọmọlede Yoruba ẹka Ipinlẹ Ondo nilu Akurẹ. Alakoso na sọ pe, awọn ti o nkẹkọ imọ nipa ede Yoruba ni awọn Yuni–

(Woju Ewe Kẹjọ)

ADAJỌ Ile ẹjọ Magistrate kan nilu Kabba ni Ipinlẹ Kwara, ti paṣẹ pe ki a ko awọn ọmọ baba mẹfa kan lọ ile ẹjọ giga lati lọ koju ẹsun dida ile ẹjọ atọwọda silẹ ati fifi girimọkai mu enia lati mu aṣẹ ile ẹjọ atọwọda na ṣẹ.

Awọn ọmọ baba mẹfa na ni: Alhaji Adeṣina Sunmọnu, Alhaji Audu Musitafa, Alhaji Umoru Sunmonu Malam Ọbaro Sunmọnu, Alhaji Salawu Gẹgẹ ati Malam Yakubu Mustafa ti Iyamoye ni agbegbe Igbimọ Ijọba Ibilẹ Oyi ni Ipinlẹ Kwara.

Awọn afẹsunkanni fi ẹsun kan awọn ọmọ baba mẹfa na pe, nwọn da ile ẹjọ silẹ lai ba ofin mu, nibi ti nwọn ti ṣe ẹjọ obinrin kan ti nwọn fi ẹsun ajẹ kan.

Nwọn ni awọn odaran na fi ẹsun kan obinrin kan ti njẹ Awawu Salawu pe, oun ni o pa Malam Salawu jẹ ni ọjọ kọkandinlọgbọn oṣu kejila ọdun 1973 ni Iyamoye.

Awọn afẹsunkanni sọ pe, labẹ ẹsun yi, awọn ọdaran na ṣe idajọ le Awawu Salawu l'ori pe oun ni o pa Malam Salawu jẹ.

Nitorina gẹgẹ bi awọn afẹsunkanni ti wi, awọn ọdaran na ti obinrin na ni ọpọnpọn lọ si ibi saree oloogbe na, nwọn si fi girimakai fun obinrin na ni omi ti nwọn fi wẹ oku Salawu mu.

Siwaju si i, awọn afẹsunkani sọ pe, lẹsẹkẹsẹ ti nwọn ṣe eyi tan ni nwọn ba gbe obinrin ti nwọn fi ẹsun ajẹ kan na kuro ninu ilu, nwọn si lọ gbe e ju si igbo.

Nigba ti ẹjọ na tun waiye nile ẹjọ Magistrate ilu Kabba ti nwọn kọ ko awọn ọdaran na lọ tẹlẹ, ni Ṣajẹnti Ọlọpa kan ti o nka ẹsun si awọn ọdaran na l'ẹsẹ, Ọgbẹni Agonwo Eke ti sọ fun ile ẹjọ na pe, awọn Ọga oun sọ fun oun pe ki oun gbe ẹjọ na lọ sile ẹjọ giga nibi ti nwọn yio ti tara ṣe ẹjọ na.

Nigbana ni Adajọ ile ẹjọ Magistrate na paṣẹ pe ki nwọn ko awọn ọdaran na lọ sile ẹjọ giga nilu Lọkọja.

## Kiko Aafin Sohun Ogbomoso

FACE ONE FINAL LAUNCHING FUND OF ṢỌHUN'S PALACE.

EYI ni lati kede pe ni ọjọ kẹsan oṣu kẹrin ọdun yi (9/4/77) ni a o ṣe aṣepari ikowọjọ fun igbesẹ kinni lori eto kikọ Aafin Ṣọhun Ogbomọṣọ, eyi ti yio waiye ninu Gbọngan ilu Ogbomọṣọ ni deede agogo mẹwa owurọ.

Gbogbo enia ni a pe nile, l'oko ati ni idalẹ. Ẹ ma ṣe alaiwa o nitoripe " Aṣetan ni i mu iṣẹ ni oriyin ".

IGBIMỌ IKỌLE
(Olukede)

WENTEC
1955

## Wa Ko'se Ero Riro!

AWỌN ONIṢẸ TI A NPE NI W. N. T. C. NFẸ ỌMỌ IṢẸ TI WỌN YIO KỌ N'IṢẸ ẸRỌ RIRỌ. ỌMỌ IKỌṢẸ GBỌDỌ

(a) MỌ IWE KIKỌ NI EDE OYINBO
(b) NI IWE ẸRI IWE MẸFA, MỌDA TABI TI IWE MẸJỌ LỌWỌ
(c) JẸ ỌMỌ ỌDUN 16 SI 18

ỌMỌ IKỌṢẸ YIO MAA GBOWO IWA—NKAN—JẸ T'Ọ JỌJU.
TETE KỌWE KI O SI FUN 'RA RẸ MU U WA SI IBI IṢẸ WA NI DUGBẸ NI ỌJỌ AJE (MONDAY) ẸTI, (FRIDAY) LARIN AAGO MẸJỌ AARỌ SI MEJILABỌ ỌSAN ATI LATI AAGO MEJI SI MẸRIN ỌSAN. MAA BỌ TAARA SI:

**Western Nigerian Technical Company Limited,**

P. M. B 5140 PHONE 22361/2
DUGBẸ ONIMATIRẸSI,
IBADAN.

# ATIORO OMO ATIALA

## Oore t'o dara (3)

A ti sọ fun nyin
Pe, o l'oju
Oore ti a le se
T'o le ba Ọlọrun nile.
A si sọ nipa
Ọpọ oore enia
Ti nwọn nṣe
Ti ko l'abọ;
Eyi ti ko l'abọ yi ni
Ọlọrun Ọba kọjalẹ
Ti ko san ẹsan
F'ẹni t'o ṣe e gbogbo.
Awọn enia
T'o ba ṣe iru eyi
L'o maa nsọ pe,
Oore t'awọn ṣe ko l'abọ.
Ki ng to maa sọ
Iru oore ti ko tọ
At'iru oore t'o tọ;
Mo kọ fẹ
Ki o ye nyin pe;
Enia kọ o,
Ọlọrun Ọba nikan
Ni i san oore
Bi o tilẹ jẹ
Pe, ọmọ enia ni
Ọba Oluwa mi yio lo.
Idi ọrọ niyi
Ti nwọn fi nsọ pe:



"Bi a ba ṣe
Enia kukuru loore,
Enia gigun
Le san an pada".
Bi o ba nṣoore
T'ẹni o ṣe l'oore
Ko f'oore san oore;
Ma binu,
Ma rero-kero;
Ma ṣe rẹwẹsi rara
Ma si ṣe kabamọ oore
Nitori Odumare nikan
L'o m'ẹni ti yio lo
Fun aarọ.
Kiki ki o sa ri i pe,
Oore t'Oluwa fẹ ni
O nṣe ninu oore;
Bi o ba ti nṣe
Oore t'Edumare fẹ,
Iwọ ma wulẹ ṣiyemeji,
Nitori
Ọlọrun Ọba
Ti i san oore nikan
L'o mọ ẹni
Ti yio ran si ọ;
Lati san ẹsan oore; bo
Iwọ le ṣ'oore f'Oyin
K'Edumare ran
Enia dudu
Tabi ki o ran Mọlato
Lati sesan oore.
Mo si tun fẹ ki o ye ọ
Pe, ilẹ ẹsan
Oore Ọlọrun ki i su.
Iwọ le ṣ'oore l'oni
Ki o to ogun ọdun
K'Olodumare to sesan;
O le san fun ọ kia.
O le san an l'osu mẹfa;
O si le ma san an
Ki o to kuro l'aiye
O le jẹ pe,
Ọmọ rẹ ti o bi
Tabi ọmọ-ọmọ rẹ ni
Oluwa Ọba
Yio san l'ẹsan oore,
Nitori Edumare nikan
L'o sa mọ
Igba t'ẹsan ooreyẹ
Awa ọmọ enia.
Nitorina:
Ẹni ba ṣoore l'oni,
Ani t'o ṣe oore
T'o ba Oluwa nile;
Bi ko ba ti i r'abọ,
K'o ma binu,
K'o ma rẹwẹsi;
K'o ma si dekun
Iṣẹ oore ni ṣiṣe;
O da mi loju to ada
Pe, eesu enia ni i gbe,
T'Ọlọrun Ọba ki i gbe
B'o ti wu ko jinna to,
Olodumare
Yio sẹsan oore
Kiki ko sa ti jẹ pe
Oore t'Ẹlẹda fẹ
L'a nṣe nigbakugba.
Njẹ gbogbo enia pata
Ti ngbọ Nasia yi,
A fẹ ki ẹ jọwọ,
Ẹ maa fiiye si
Ọro wa gbogbo
Nitori a nṣe
Ẹknnrẹrẹ alaye
Bi a ti nṣẹ Nasia.
Bi ẹ ba ranti
A ti sọ fun nyin
Pe, oore dara
Ki a maa ṣ'oore
Ni ile aiye
A sọ pe k'a lakaka
K'a maa ṣ'oore
F'ẹnikeji;
A si ṣalaye
Pe, meji loore pin si
Oore t'Ọlọrun ko fẹ
At'eyi t'Ọlọrun fẹ.
Asọ b'o ṣe jẹ
Pe, Ọlọrun Ọba
Ni i san oore
F'ẹni t'o ba nṣoore
T'o tọ niwaju Oluwa
Oun l'o si mọ
Enia ti yio lo
Lati san ẹsan oore pada
A si tun sọrọ
Pe, bi a ba nṣoore
K'a ma kanju
Aarọ oore ti a ba ṣẹ,
Nitori Edumare nikan
L'o mọ igba
Ti yio wọ
Lati san aarọ
A si nfọwọsọiya
Pe, b'o ti wu k'o pẹ to,
Ọba Odumare
Ko ni i ṣalai san
Ẹsan oore t'o ṣe gbogbo
Bi Ẹlẹda ba wa fẹ,
A o sọ nipa
Iru oore ti ko t'ọna
B'o ba d'ọsẹ t'o nbọ.

ỌLỌLA ATIORO

# Ejo Sodeinde ati Banki doju ogbagade



ỌGBẸNI OLUFẸMI ŞODẸINDE

ẸJỌ "Ibalorukọjẹ" ti gbajumọ oludaṣẹsilẹ kan ni ilu Ibadan, Ọgbẹni Olufẹmi Şodẹinde pe ile ifowopamọsi kan ni ilu Ibadan ti d'oju ọgbagade bayi nitoripe arolaagun ni tọtuntosi nrojọ, bẹẹ ni awilaagun ni awọn agbẹjọro wọn nwi niwaju ile ẹjọ giga kan nilu Ibadan ti o ngbọ ẹjọ na.

Ọgbẹni Olufẹmi Şodẹinde ni o pe Banki kan ti a npe ni African Continental Bank Limited (A C B) ẹka ti Ibadan l'ẹjọ irinwo ọkẹ Naira (₦8 million) fun şişe tanadi fun oun l'ori iṣẹ şişe ounjẹ ohun ọsin ti oun fẹ dasilẹ si ilu Iganna ni Ipinlẹ Ọyọ pẹlu Ẹgbẹ oludaṣẹsilẹ kan ni ilẹ Amẹrika ti njẹ Allied Mills Incorporated of Chicago, America lọwọ.

Ile iṣẹ ilẹ Amẹrika na gẹgẹ bi Ọgbẹni Şodẹinde ti wi, ni o fẹ darapo pẹlu ile iṣẹ oun ti o njẹ SHODẸINDE BROTHERS OF NIG. LTD; ti olu ile iṣẹ rẹ wa nilu Ibadan.

Ọgbẹni Şodẹhinde sọ pe, oun ni oun fẹ mu awọn Oyinbo Amẹrika na wa si ilẹ Naijiria lati jumọ da iṣẹ nn ti yio gba ẹgbẹẹgbẹrun ọşişẹ silẹ ni ilu Iganna ni agbegbe Ọyọ ni Ipinlẹ Ọyọ isinsinyi.

Ninu ẹjọ rẹ na, Ọgbẹni Şodeinde sọ pe, olu ile iṣẹ Allied Mills Incorporated Amẹrika ti oun nwi na kọwe wadi lọdọ Banki Cooprative Bank Limited Ibadan lati ba awọn wadi l'ọdọ Afican Continental Bank ti iṣe Banki ti ile iṣẹ oun nfi owo pamọ si, ki ile iṣẹ ti Amẹrika ba le mọ bi ile iṣẹ oun na lowo lọwọ daadaa.

O ni nigbati Banki Afirican Continental Bank yio kọwe si Banki Cooprative Banki l'ori ọrọ na, nṣe ni Mọnija Banki na ba ile iṣẹ oun Shodẹinde Brothers Nigeria Limited jẹ kanlẹ pe, onigbese ni ile iṣẹ

(Woju Ewe Keje)

# Akédé ọ̀nà Ìyè

# Kini yio je Aabo emi re?



WOLI S. I. OWOẸYẸ
Oniwaasu Naa.

ŞUGBỌN awọn ọrun ati aiye, ti nbẹ nisinsinyi, nipa ọrọ kanna li a ti tojọ bi işura fun ina, a pa wọn mọ de ọjọ idajọ ati iparun awọn alaiwa–bi– Ọlọrun. Şugbọn, olufẹ, ẹ ma şe gbagbe ohun kan yi, pe ọjọ kan l'ọdọ Oluwa bi ẹgbẹrun ọdun li o ri, ati ẹgbẹrun ọdun bi ọjọ kan'' 11 Peteru 3; 7–8.

Nigba ti a ba sọ fun onile oju odo pe, akoko ojo nbọ ati pe, ojo ọdun na yio pọ jọjọ ju eyi ti o ti nrọ ri lọ; kini o yẹ ki onile oju odo, ti ile rẹ ko si fi idi mulẹ daradara şe lori eyi?

Gẹgẹ bi emi şe ro o si, nşe l'o yẹ ki onile oju odo na mura si ti tun ile rẹ şe yala nipa fifi okuta tabi kankere yi ile na ka. Nigba ti onile na ba şe bayi, ojo ki yio le wole le e lori.

Bakanna bi a ba ran agbẹ kan leti pe, oko ko le şai jona laipẹ yi nitori o şe akoko ọda; ohun ti o yẹ ki iru agbẹ bẹ şe bi to ba jẹ ọlọgbọn ni ki o kọ gba bebe oko rẹ sẹhin. Bi ina ba de ko ni i de ọdọ rẹ.

Bẹẹ gẹgẹ ni Ọlọrun nke si iwọ ati emi l'oni yi pe, akoko na niyi lẹhinkule ti awọn ẹlẹşẹ yio maa jiya ẹşẹ ni gbangba A o fi ina ajooku sun ajẹ. Egun ti a ti fi oşo ati ẹni okunkun aiye gbogbo gun yio bẹrẹ si i rababa l'ori wọn.

Ani akoko na ti de bayi, ti ọpọ yio maa şi agbara wọn lo, ti iwa aşemaşe yio pọ si i. Igbe loke, igbe l'odo yio si gbodekan ninu aiye.

Njẹ nigba ti okuta ati kankere yio jẹ aabo fun ile eti odo, ti işẹ aşekara nipa gbigba eweko sẹhin daadaa yi si jẹ aabo fun ẹni ti oko rẹ fẹ gbina: Ọrẹ, kini yio jẹ aabo fun ẹmi rẹ nigba ti ewu ajakaiye nrọdẹdẹ l'ori aiye yi? Ani bawo ni iwọ yio şe bọ ninu ewu oniruru ti nbẹ l'ode yi?

Nitorina iwọ ọmọ enia, imọran mi si ọ ni pe, ki iwọ ki o dide nisinsinyi ki o tun ọkan rẹ şe ki o ma şe maa ro ero ika si ọmọnikeji rẹ laişẹ ọ.

Ani, ki iwọ sọ fun ọkan rẹ lati oni yi lọ pe ki o ma şe şiyemeji si Jesu Kristi mọ. Ani lati oni yi lọ, sọ fun ẹsẹ rẹ ki o ma şe maa yara si irin ika.

Iwọ ti o jẹ ọlọrọ, sa fun iwa ifiyajẹni; sa fun igberaga. Na owo rẹ si ọna ifẹ rere si Ọlọrun.

Iwọ alaini, ma şe maa dọdẹ awọn ti o ni lati ba tiwọn jẹ ki o ma ba ku sinu aini rẹ.

Iwọ obinrin, ma şe lo ẹwa ara rẹ fun agbere, ole, irọ ati iwa okunknu gbogbo.

Iwọ ọmọkunrin, ranti pe, ibi ti a fi şe ori, a ki i fi ibẹ tẹlẹ. Ma şe lo ipo rẹ lati fi iya jẹ ẹni ti ko to ọ. Ranti Ẹlẹda rẹ lakoko ti iya koi ti i de yi.

Bi idaamu kan tabi iya kan ba nyọ ọ l'ẹnu l'akoko yi, ronu si iwa ẹşẹ rẹ, ani awọn ẹşẹ ti o maa nko ijiya ba ni ki o si tete kọ iwa na silẹ nitoripe, ẹlẹşẹ ki yio lọ lai jiya.

O şe i şe ki ọrọ iwaasu yi koro leti rẹ, o şe i şe ki o ro ọ l'ara de egungun. Njẹ bi o ba gbọ Ọrọ Ọlọrun ti o njo ni bi ina, ti o si ti ipa gbigbọ Ọrọ na ronupiwada ti o si fi bẹẹ di ọmọ Ọlọrun a ti ajumọjogun Ijọba Ọrun; ko ha san fun ọ ju pe ki a gbe gbogbo ara rẹ ju sinu ina Ọrun apaadi bi?

Iwọ ọmọ enia, akoko na ti a o mu ọkan ti a o si fi ekeji silẹ gẹgẹ bi Bibeli ti wi, nrọgba yi aiye ka bayi. Şugbọn taa ni a o mu, taa ni a o si fi silẹ?

Ẹnikẹni ti ko ba gba Jesu Kristi Oluwa gbọ ti ko si tẹle ilana Rẹ wa ninu ewu awọn ti a o mu şugbọn ẹni na ti o ba tete ronupiwada ti o si di otitọ ati ododo Jesu Kristi mu, oun na ni a o fi silẹ ti ewu ti o nrọdẹdẹ l'ori aiye ki yio wu.

Nitorina iwọ ọmọ enia, kini yio jẹ aabo fun ẹmi rẹ ni ọjọ ewu? Aya fi bi o ba gba ọmọ Ọlọrun gbọ ti o si gba A l'aye ninu ọkan rẹ, ninu iwa ati işe rẹ ati ninu aiye rẹ.

ADURA

Oluwa, Ma şe mi ni asinniwaiye, Aamin.

## Lati Owo Woli S. I. Owoeye


**NIGERIA NEW STATE CO.**

Jẹ atẹwe asiko. Bi o ba fẹ tẹ oniruuru iwe: Kalẹnda, Almanak ati bẹẹbẹẹ lo, Ile Işẹ wa wa ni:

18, Ọdunlami Street,
Phone 27017, Lagos.



**IWE ỌRỌ ỌLỌRUN**

Fun anfani ẹnyin ti o şoro fun lati ri iwe mi yi ra ni ọkookan, mo ti şeto lati maa fi apapo iwe na şowo si nyin ni aadota Kobo (50k) pere.

1. ADURA AIYERAIYE
2. IBANIWI OLUWA
3. KINI ILE AIYE ŞE BAJẸ?
4. Ẹ JOWO ARA NYIN FUN OLUWA

Bi o ba ti fi Postal Order 50k şowo si mi, ng o fi apapọ iwe na şọwọ si o lagbara Oluwa, Fi owo ranşẹ si:

Woli S. I. Owoẹyẹ
Box 1206,
Ibadan.



**Apprentices Wanted**

LEARN to become a successful printer; learn on modern machine with modern technique.

Parents, don't waste the time of your fresh Primary Six & Modern III School leavers; send them to learn modern printing, Ma— chine operating and Book-binding from us. Apply personally today.

The Works Manager,
(Imọlẹ Owurọ)
N4/496B Yemẹtu Aladorin,
Ibadan:

# ÌSỌ̀RỌ̀-N'ÌGBÈSÌ...

## IPADE (49)

NINU ipade ọsẹ ti o kọja bi ẹ ko ba gbagbe ni Lawuyi Ogunniran gba gbogbo akoko, o si sọrọ pupọ nipa iwa gbogbo eniyan dudu si ara wọn. Lẹyin ti o ti mẹnuba ọpọ iwa ti awọn orilẹ-ede eniyan dudu nhu si ara wọn tan ni o wa kaanu pe, oun ko ri i ki nwọn yipada kuro ninu iwa na lẹyin ọdun aṣa ibilẹ na. Ki a ma wulẹ sọrọ pupọ mọ, Iroyin Ipade wọn ti ọsẹ yi lọ bayi.

Adeyẹmọ Ojẹrinde

L'ỌSẸ t'o kọja, ọmọ Ejigbọjọ,
Iwọ nikanṣoṣo daaya
L'o sọrọ delẹdelẹ;
Koda, lat'Ijọ a ti npade,
Ko ti i ṣẹlẹ ri pe, ng ko wi nkankan.
Eyi ti a ṣe gbẹyin yi
L'o ṣ'akọkọ lat'igba ibẹrẹ.
Ki a ṣooto, ọmọ Ejigbọjọ,
Otitọ l'ọrọ rẹ gbogbo t'o o sọ;
Otitọ l'o jẹ, irọ kan ko si nibẹ.
Ng ko mọ pe
Ibi t'o b'ọrọ lọ niyi ọmọ Ejigbọjọ,
Ọlọrun ngbọ, o ko kuku ṣiṣọ,
Otitọ ọrọ l'o jẹ ti njo ni,
T'o si nm'ọkan wariri.
Ayinde, Maa gbọ ọmọ Ejigbọjọ,
Mo fẹ ki o dakun, gba mi l'aaye
Nitoripe, ọrọ nlanla l'o mu wa
O si yẹ k'emi na o le sọ si i gidi
Ki i ṣe ọrọ lasan
Ti a le f'ọwọ rọ ju sẹyin.
Mo ranti ohun oju ri
N'ile Aganyin l'aiye Kuame:
T'o ṣe ofin alagidi
Pe, ajeji ko gbọdọ mu owo Ghana
K'o ko o de'lẹ rẹ gbogbo;
O l'eniyan ti ko ba wọ fun,
K'o fi Ghana silẹ.
Walahitalaahi, ọmọ Ejigbọjọ,
Owo iyawo ti mo kọ ri,
O nbẹ ni Ghana ti ko le jade
Ng ko le r'ajo aimowowale
L'o jẹ ng fi Ghana silẹ.
Mo tun wa ranti ohun to ṣẹlẹ,
Nigba ogun Ojukwu ti a ja nibi,
Ṣebi, ọpọ ilẹ eniyan dudu
Ni nṣe t'Ọlọtẹ ilẹ wa;
Ọpọ nṣe ti Naijiria l'oju,
Nwọn nf'inu ṣe ti "Biafara".
Ọpọ l'o tun nbinu wa
Nitori ti a lowo lọwọ;
Ọpọ nṣagbẹnuku
Nitori a tobi, a si niyi;
Ẹ ko w'ohun oju ọmọ Naijiria nri
Nibi nwọn nṣowo kiri;
Bi nwọn ba le Naijiria tan,
Nwọn a gba ohun ini rẹ!
Ayinde ! Ma sọ p'ọrọ mi pọju,
Nṣe ni mo njẹri s'ọrọ rẹ ti o sọ ni
Nitori, awa na ko kere,
Gbogbo rẹ l'a mọ.
Ki l'anfani ẹni ti a fẹ,
Ti ko fẹ ni rara?
Ki l'anfani aṣepọ ti a ni
Ti ko wulo ?
Naijiria nfun wọn l'ẹbun,
O nfun wọn l'owo afẹ,
O nran wọn lọwọ kiri
N'ilẹ Afrika l'abẹ ajọṣe,
Sibẹ, ibi ni nwọn fi nṣe Naijiria.
Bi a ba tilẹ sọ pe ailaṣepọ tẹlẹ
L'o fa iru iwa yi,
Ọjọ ti a ti wa ninu Ẹgbẹ
Ti a jọ nṣ'ẹgbẹ iṣọkan wa (O.A.U)
Ki l'ayipada iwa
Ti nwọn hu lẹyin ọrọ ?
Bi a ba si wi pe,
Eyiini ko too pọnlẹ,
Lat'ijọ ati ṣ'ọdun aṣa tan,
Ki lo wa de
Ti ko s'ayipada ninu iwa ibi
Ti nwọn nṣe si ara wọn?
Ki l'awọn Eebo kuku ṣe wa
Ti a fi ni ki nwọn m'ori wa?
Iwa wo l'Eebo hu wa
Ti a fi nṣepe, ṣepe?
B'Ebo tilẹ huwa ẹṣẹ,
Bi babanla Eebo tilẹ ṣe ibi
Fun babanla gbogbo wa
Ọpọ anfaani ti wiwa Eebo mu wa
O san l'ọna ẹgbẹẹdogun ju
Iwa ibi ojoojumọ
Ti nbẹ lọwọ Dudu si Dudu lọ.
Ayinde ! Maa gbọ ọmọ Ejigbọjọ
Nitootọ ni ọrọ yi koro l'eti
Ṣugbọn yio dara fun wa
Bi a ba gbagbe ọrọ ana
Ti a ba nb'Eebo ṣ'ọrẹ imulẹ.
Nitori gẹgẹ bi orin
Ti Olorin maa nkọ l'oke ẹgan wa pe;
"B'ara ile ko ba ba ni ṣe,
K'a si maa b'ara adugbo ṣ'ọrẹ,
K'a jọ maa gbimọran pọ;
Ki l'o ha jamọ?
Ẹni ti a fẹ ti ko fẹ ni
Ki l'o ha jamọ?"

Lawuyi Ogunniran

O ṣehun l'aiye ọmọ Ajiṣegiri;
Gbogbo b'o kuku ti ri
L'o ti la silẹ.
Bi a ba w'orere ọrọ yi,
"Gọngọ" ki l'o sọ
N'ibi aṣa ibilẹ ti a ṣe lọ?
Iru anfani t'o wu ko mu wa,
Njẹ gbogbo ẹsun ti a ka wọnyi
Ko ba ti sọ gbogbo rẹ di "Iraa"?


L. Lawal Tips

2
9
11

For three Sure Bankers
Write or come to:-
E1/391 Labiran Street,
Ibadan.
N.B:- Ask Of Baba Ṣẹri.

POOLS! POOLS!

Sulu Special Nap

10 34
3 9 45

Hacco Tip: 8 11 22

IWE IGBAẸLODE DARA PUPỌ. RA TIRẸ NIBẸ

1. Iwe gbogbo Agbo Ọmọde ati Agba 20k
2. Kurani ọgọta esu ni ede Yoruba N10 Esu kan (50k)
3. Yasin ni Yoruba ati Isawaka 50k
4. Zabura ati itumọ (N1)
5. Zabura Yoruba (N1)
6. Iwe Aiye Akamara (N1)
7. Iwe Eniaṣoro (N1) Adedẹwẹ (50k)
8. Iwosan Ajẹọidan Ogun enia dudu (N5); Kekere (75k)
9. Iwe ala ati ala (N2)
10. Kekere (50k)
11. Iwe Oogun iwosan (N2.50) Kekere (75k)
12. Itan Anabi ati Yisa (N1)
13. English Hausa Yoruba & Ibo Registered No 410 (50k)

FI OWO ATI STAMP (5k) RANṢẸ SI:

(1) Alufa Yisa Igbaẹlode N2/394a Odoye Adeọyọ Rd, P. O. Box 3365, Mapo—Ibadan



(2) Alufa Igbaẹlode, Mọṣalaṣi Idi-Işin St, Isalẹ Koto P. O. Box. 17 Ilorin

# Ẹ gbọ t'emi

## Ijanba moto poju

OLOOTU,

ỌRỌ moto ti o npa enia bi ẹni pa ẹran yi ti buruju ni ilẹ Naijiria *n*itoripe ọpọlọpọ enia ni ijanba moto ti ran lo si orun apapa-ndodo.

Ẹnu ojo mẹta yi ni moto pa awon omo ile iwe Jẹleosinmi, oluko won ati aladugbo kan ni Ọja-Igbo nilu Ibadan.

Bi a ba ṣakiyesi ohun ti o nfa ijanba moto yi daradara, a o ri i pe, wiwa mọto ni iwakuwa tabi ki nwon maa gbe moto ti ko dara kiri l'o nfa opo ijanba na.

Nitorina, mo ro Ijoba ilẹ Naijiria lati wa nkan ṣe lati din ijanba moto ku ni ilẹ wa.

Mo ro Ijoba pẹlu lati ṣe awon ona wa jakejado Naijiria daradara, ki nwon la titun, ki awan ti o ti wa tẹlẹ gba ọkọ meji tabi merin leekan na. Mo rọ Ijoba Ipinlẹ Ọyo lati so iru ona Eṣu Awẹle ti o ti Ọja-Iba nilu Ibadan jasi Ọranyan di ona kanṣoṣo nitori ona na họ pupọ tobẹẹ ti o jẹ pe, ko rorun fun moto meji lati pade.

Bi Ijoba ba le gbe imọran mi yi yẹwo ti nwon si tẹle e, o da mi l'oju pe, ijanba moto yio dịnku daradara ni ilẹ wa

Emi ni,
Alhaji Busari Salami,
Ibadan.

36

# E da ofin amu-gbo pada si odun mewa

OLOOTU,

ỌPỌ iwa odaran, ipaniyan, isinwin ati irufin gbogbo ti o gbodekan ni ilẹ Naijiria l'oni yi ni o jẹ pe igbo mimu ni o fa a.

Tẹlẹ, enia ti nmu igbo ko to nkan nigba ti nwon ti ṣofin pe ẹwon odun mẹwa ni ki nwon maa ju ẹni ti o ba mu igbo si; ṣugbon lẹsẹkẹsẹ ti Ijoba Ologun ti sọ ẹwon odun mẹwa na di oṣu mẹfa ni awon amugbo ti wa po si i ni ile wa.

L'oni ni ilẹ Naijiria, nṣe ni awon enia nmugbo bi ẹni mu siga lai tilẹ bowo fun ofin mo; o si fẹrẹ le jẹ pe gbogbo ile iṣẹ jakejado ilẹ wa ni amugbo wa.

Awon omo ile iwe giga ti sọ igbo mimu di ara ounjẹ oojo won, eyi ni o si fa a ti ijongbon fi maa nbẹsilẹ nile ẹko

(Woju Ewe Kẹfa)



ỌGAGUN AGBA O. ỌBASANJỌ
Alakoso Ijọba Naijiria


# IFỌKANBALẸ ORI KẸKẸ



N625.00

**Awọn ọwọọ Suzuki GT**

Alupupu alagbara 125cc tabi 180cc Suzuki GT125 ati 185. Alupupu GT 125 ti a fi agbara diẹ kun yi, yio gbe ọ rin ibusọ ọgọfalemẹjọ ni wakati kan, GT185 yio si gbe ọ rin ibusọ mẹrindinlogoje ni wakati kan, labẹ akoso rẹ.
Bi o ti ngbesẹ le amuro wọn ni nwọn nduro sẹmu laini ifoya iṣubu. Suzuki GT ki ngbani l'agbara lati mu ṣiṣẹ nwọn si ni agunki onipele marun ni ọwọ ẹyin, ti ki yio je ki o mọ ala ile yangi. Ọwọọ Suzuki GT jẹ alupupu afẹ.
Ọwọọ Suzuki meji wọnyi ki ntilẹ gbona ju. O ko ni ifoya pe nwọn le bu mọ ọ ni di.

Ra ifọkanbalẹ, ra ailewu, ra ilọsiwaju, ra Suzuki 125cc, bi o si fẹ eyi ti o l'agbara diẹ sii, ra 185cc.

SUZUKI Alupupu ti ngbenigunlẹ layọ.

# Irohin ni Onilũjilú

## New—Busa

NWỌN ti mu awọn Ṣọja Naijiria mẹta ti nwọn jẹ ara Ẹgbẹ ologun 185 Infantry Battalion, New Busa ni Ipinlẹ Kwara wa sile ẹjọ Magistrate ilu na lati koju ẹsun pe, nwọn lu obinrin kan ni anapalara.

Awọn ọdaran na ni Jacob Odui, Johnson Obuza ati Gabriel Rabo.

Awọn afẹsunkanni ka ẹsun si awọn enia na l'ọrun pe, ni ọjọ kejidinlọgbọn oṣu kejila ọdun ti o kọja ni nwọn na onisowo kan, Iyaafin Nimọta Fidipọtẹ ni ọja New Busa, nwọn si pa a l'ara.

Nigba ti nwọn nrojo na nile ẹjọ, awọn Ṣọja mẹta na so pe awọn ko jẹbi. Adajo ile Ẹjo si ti fi ojo idajo si ojo keje oṣu kẹrin odun yi.

## Eko

ILAIPẸ yi ni awọn omo Ẹgbẹ Jolly Brothers Circle ṣe ajodun kinni Ẹgbẹ won ni ile olori Ẹgbẹ won, Ọgbẹni Tajudeen Atobajaiye ni 17, Maranmi St; Igbobi, Yaba ni Ipinlẹ Eko. Ẹṣe gbogbo omo Ẹgbẹ l'o pe sibẹ.

Alufaa Saliyu Ọloṣọ, Alhaji Abudu Raṣidi, ati Jamiyu l'o ṣadura fun won nibi ajodun na.

Ara awon omo Ẹgbẹ na ni Tajudeen Atobajaiye, Mukaila Ajasa, Musibau, Mufutau, Adebayo Aiyerogbon, Tunji Folami, Rafiu Ọmolaja;

Musibatu Atobajaiye, Abibatu Ajasa, Silifatu, Amudatu Fuja, Fausatu Arogundade, Idayatu Ayoka, Abimbola Rafiu, Ainatu Aiyerogbon.

## Katsina

KANSILỌ fun eto eko ninu Igbimo Ijoba Ibilẹ ilu Katsina ni Oke-Ọya, Alhaji Abba Kalli, ti kilo fun awon obi ni ilu na lati dẹkun mimu omobinrin won kuro nile iwe nitoripe nwon fẹ sin won f'oko.

Kansilo Kalli ṣe ikilo yi nitori irohin ti o gbile ni ilu na pe, nṣe ni opo obi nlo mu awon omobinrin won kuro nile ẹko ti nwon si nfa won lo sile oko.

Siwaju si i, Kansilo Kalli so pe ni ona kinni, nṣe ni iru awon obi na njẹ ki owo ti Ijoba nna lati fi ko iru awon omo bẹẹ l'ẹko ja si asan ati pe nṣe ni iru iwa bẹẹ yio mu ki agbegbe Katsina

di ero ẹhin l'ojo iwaju.

Kansilo na wa kesi gbogbo obi nilu Katsina lati jẹ ki awon omo won kẹko daradara ki igbesi aiye awon obi ti omo ati agbegbe won ba le ro won l'orun l'ojo iwaju.

## ILA—ORANGUN

IROHIN kan lati ilu Ila-Ọrangun ni Ipinlẹ Ọyọ fi ye wa pe ni ọjọ Iṣegun ti iṣe ọjọ kejilelogun oṣu keta odun yi ni Alaga Kansul Ila-Ọrangun Ọmọ Ọba Isaac Adebayọ bẹrẹ irinajo "mọ-mi-ng mọ ọ" kaakiri Kansul na.

Ọjọ meji pere ni Ọmọ-Ọba Adebayọ fi rin irinajo na ninu eyi ti o bẹ Ọba, awon Ijoye ati sanmori ilu wo.

Bakanna ni Alaga na bẹ awon ẹka ile iṣẹ Igbimo Ijoba rẹ wo pẹlu.

Ọmọ-Ọba Adebayo sọ ero rere ti Kansul rẹ ni lokan fun gbogbo enia, o si ro won lati fowosowopo pẹlu oun ati awon Kansul oun ki awon le kogbajari.

## Abeokuta

ỌWỌ awon Ọlopa ilu Abeokuta ni Ipinlẹ Ogun ti tẹ awon enia mẹjo kan ti nwon so pe nwon fura si pe nwon le ran awon lowo l'ori ẹṣẹ ifipajale ti o ṣelẹ ni Ipinlẹ na.

Ọga awon Ọlopa otẹlẹmuyẹ fun Ipinlẹ na tilẹ so pe ni osẹ ti o nbo ni awon enia ti awon mu na yio f'oju ba ile ẹjo.

# 35

## ofin amugbo

(Lati Oju Ewe Karun) giga nigbagbogbo.

Bi a ba kiyesi ile wa l'ode oni, opo odomode l'o ti di asinwin nipa igbo mimu, opo odaran ati arufin l'o si wa kaakiri ile wa.

Bi a ba nwo eyi ni iran bẹẹ, njẹ olukuluku enia ki yio wa ninu ewu nigba ti o ba ya ?

Ẹ wo opo adigunjale l'ode oni ti nwon npa onidukis sinu ile ti nwon si nfo ile iṣẹ nlanla tabi Banki losangan gan, ẹ ko mo pe igbo mimu ni ohun elo pataki ti nwon fi nṣiṣẹ na?

Nitori ki alaafia ara, ailewu lori ẹmi ati dukia olukuluku le wa ni ilẹ wa, mo nro Ijoba Ologun Apapo Naijiria lati fagile ofin oṣu mẹfa ti o wa bayi l'ori igbo mimu, ki nwon si ṣofin pe ẹwon odun mẹwa ni ki ẹni ba mu igbo maa lo ki ẹni ti o ba si ngbin igbo maa lo si ẹwon gbere.

Bi nwon yio ba so pe ofin alailaju ni, ẹ jẹ ki nwon wi bẹẹ, bi okan wa ba balẹ l'orilẹ-ede wa o san ju ki a pe wa ni olaju ki a si wa ninu ipaiya awon odaran oloṣa, arufin, rogbodiyan ile iwe ati bẹẹbẹẹ lo.

Ọpo awako pẹlu ni o jẹ pe nipa igbo mimu ni nwon fi ngba ẹmi opo enia. Oro yi yẹ ni apero fun ẹnyin Alaṣẹ.

Emi ni,
Adeṣola Adegbindin,
Ọyọ.


## Yasin ati Isawaka

EYI ni lati kede fun ẹnyin onibara wa ti ẹ ti nkowe si wa lati ojo pipẹ pe, a ti ni Yaasin ati Isawaka ni ede Yoruba ati Wutuba rẹ.

Adura pataki ni fun Musulumi. 50k ni Ẹyokan, ₦2. ni Dosinni rẹ.

Tete fi owo ranṣẹ si:-

Alufaa Igbaẹlode
(1) N2/394A Odoiye
Adeoyo Rd,
P. O. Box 3365
Mapo, Ibadan

(2) Alufaa Igbaẹlode
Moṣalaṣi Idi Iṣin St;
Iṣale Koto,
P. O. Box 17
Ilorin

KEREO

GBOGBO - ENIA!

fun

•Ipolowo ọja ati Ikede,
•Akiyesi ati Itufọ,
•Iranti oku ati Ikede Ariya,
•Ikilọ ati bẹbẹ lọ;
•Tabi Almanak ati Kalẹnda titẹ.

DARAPỌ PẸLU AWỌN ỌLỌGBỌN ENIA TI O NṢEE SI INU (IMỌLẸ OWURỌ) TI O GBAJUMỌ KARI AIYE. OWO TI A NGBA KOPỌ, SA KỌWE TABI KI O WA RI:-

Advertisement Manager:

IMỌLẸ OWURỌ
N4/496B YEMETU ALADỌRIN,
P.M.B. 5230, IBADAN.

# Nwon lu iya arugbo pa nitori airo ojo

IROHIN lati ilu Akurẹ ni Ipinlẹ Ondo fi ye wa pe, awọn enia kan ti sọ oko pa iya arugbo kan ni ilu na nitori ojo ti ko rọ yi.

Gẹgẹ bi a ti gbọ, nwọn ni nigba ti 'ajẹ' na nka pe oun ni ko jẹ ki ojo rọ; ni inu bi awọn enia ti nwọn si sọ ọ ni okuta pa lẹsẹkẹsẹ.

Irohin miran lati ilu Akurẹ fi ye wa pe, airọ ojo yi mu wọn kaka ni ilu na tobẹẹ ti awọn enia fi nwa ojo ni ọnakọna.

Gẹgẹ bi a ti gbọ, nṣe ni awọn kan ninu ilu nsọ kiri pe ojo ki yio rọ ayafi bi awọn agba egungun ilu na ba fa ojo pẹlu agbara airi wọn.

Irohin na sọ pe o ṣe iṣe ki Igbimọ Ijọba Ibilẹ Akurẹ bẹ awọn egunguu na lọwẹ lati fa ojo nitori Alaga Kansul na, Ọgbẹni Kọla Ogun--gbade sọ pe, oun ni igbagbọ gidigidi pe awọn egungun na ni agbara lati fa ojo, o si yẹ ki awọn kesi wọn lati dan agbara wọn na wo.

Alaga na sọ siwaju si i pe, nwọn ti pe awọn egungun na lati fa ojo nigbakan ri ti ọgbẹlẹ nla ṣẹlẹ ni ilu Akurẹ.

Ṣaaju iṣẹlẹ wọnyi ni Gomina Ologun Ipinlẹ Ondo, Ọgagun David Ita Ikpeme sọ pe, airọ ojo ni o jẹ ki omi ti njade ninu ẹrọ afami ni Ipinlẹ na dinku.

## Oluko Yoruba

(Lati Oju Ewe Kini)

fasiti wa ko to nkan rara, eyi l'o si fa a ti o fi jẹ pe awọn olukọ ede Yoruba ṣọwọn pupọ ni awọn ile ẹkọ giga Ipinlẹ na.

Nigbana ni Alakoso na rọ Ẹgbẹ olukọ na lati maa fi imọ gbogbo nipa ede ati aṣa kọ awọn akẹkọ wọn nipa eyi ti nwọn yio fi ni iwuri si kikọ ẹkọ ede na ni Yunifasiti.

Bakanna ni Dokita Fọlayan rọ Ẹgbẹ na lati maa gba awọn olukọ ede Yoruba niyanju lati maa kọwe l'ori ede Yoruba. Alakoso na si kan saara si awọn Akewi ati onkọwe gbogbo ti o mu ede Yoruba gbegba oroke.

FOR ALL YOUR

Electronics:

Fans, Cookers, Radio sets, T. V. sets, Colour T. V. sets, coolers etc: at reasonable prices

PATRONIZE

Aiyedetisola

Commercial

Stores:

AN27 I.C.C. Stall
AGODI GATE
IBADAN

## POOLS! POOLS!!

| OUNJẸ | ỌMỌ | NAP | ŞEKẸ | NAP |
|---|---|---|---|---|
| 11 | 17 | | 2 | 6 |
| 18 | 19 | | 25 | 32 |

**5 12 22 43**

Printed and published by the People's Star Press Limited, [illegible] Ibadan. Olootu (Editor) Lawuyi Ogunniran, [illegible] Adekile Ibadan. Lagos Office: 16 Odunlami St. Phone 27917.